# AWỌN AMUYẸ TI IYAWO KRISTI

**Owe 31:10-31; Matteu 25:1-30; Ifihan 2:1-4**

**ẸKỌ 363 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Ẹ jẹ ki a yọ̀, ki inu wa ki o si dùn gidigidi, ki a si fi ogo fun u: nitoripe igbeyawo Ọdọ-Agutan de, aya rẹ̀ si ti mura tan" (Ifihan 19:7).**

**I Iyawo Kristi Ri Gẹgẹ Bi Obinrin Oni iwa-rere**

1 O jẹ ẹni ti o ṣe e gbẹkẹle, Owe 31:10-12; Matteu 24:45-47

2 Oun a maa fi tinutinu ṣiṣẹ, Owe 31:13-19, 22-25; Gẹnẹsisi 24:18-20

3 Oun jẹ́ oninurere a si maa ran alaini lọwọ, Owe 31:20, 26; Orin Dafidi 112:9; Jakọbu 1:27

4 Oun ki i ṣe ọ̀lẹ tabi alainaani, Owe 31:21, 27; Heberu 2:3

5 Ibẹru Oluwa ni o mu ki o maa so eso ti o ni iyin bayii, Owe 31:28-31; Orin Dafidi 111:10; Owe 22:4; Isaiah 11:2

**II Owe Wundia Mẹwaa**

1 Wundia mẹwaa duro de bibọ̀ ọkọ iyawo, Matteu 25:1-9

2 Ọkọ iyawo dé, a si pin wọn niya, Matteu 25:10-13

**III Owe ti Talẹnti**

1 A ṣe ipinfunni talẹnti a si mu wọn lò, Matteu 25:14-18

2 Oluwa pada bọ̀ a si ṣe ipinya, Matteu 25:19-30

**IV Iṣẹ ti a Rán si Ijọ Efesu**

1 A yin ijọ naa fun ohun pupọ, Ifihan 2:1-3

2 Ṣugbọn ṣá o ti fi ifẹ iṣaaju silẹ, Ifihan 2:4

## ALAYE

### Iyawo Alailabawọn

A ṣe apejuwe iyawo Kristi gẹgẹ bi "ijọ ti o li ogo li aini abawọn, tabi alẽbu kan, tabi irú nkan bawọnni" (Efesu 5:27). O jẹ "wundia ti o mọ́" (2 Kọrinti 11:2), "o wọ aṣọ ọgbọ wiwẹ ti o funfun gbõ" (Ifihan 19:8). Isọdimimọ́ -- ti i ṣe àyà funfun -- jẹ ọsọ ti o ti gba nipa Ẹjẹ Ẹni naa ti o fi ara Rẹ̀ fun un; o si gbọdọ pa ara rẹ̀ mọ́ kuro ninu ayé ni aini abawọn, ki o si maa rin ni iwa mimọ ni ọjọ ayé rẹ̀ gbogbo. Bawo ni o gbọdọ ṣe maa rin pẹlu ikiyesara tó, ki o le jẹ ọ̀kan ninu awọn "ti a pè, ti a yàn, ti nwọn si jẹ olõtọ" (Ifihan 17:14). Sibẹ ipe yii ṣi silẹ fun "ẹnikẹni ti o ba fẹ" lati jẹ Iyawo Kristi.

### Ṣiṣe e Gbẹkẹle

Ẹ jẹ ki a ṣe akiyesi awọn wọnni ti wọn jẹ Iyawo gẹgẹ bi obinrin oni iwa-rere ti a ṣe apejuwe rẹ̀ ninu Iwe Owe 31:10-31. O ṣe iyebiye to bẹẹ ti iye rẹ̀ kọja iyùn. Ki ni o sọ ọ di bẹẹ? "Aiya ọkọ rẹ̀ gbẹkẹle e laibẹru." Bi o ba fa bibọ Rẹ̀ sẹyin fun ọdun kan tabi bi o ba fa bibọ Rẹ̀ sẹyin fun ọdun mẹwaa, ki yoo su u, bẹẹ ni ki yoo rẹ ẹ ki o si bẹrẹsi i fi ifẹ rẹ fun aye, ki o si maa gbá awọn ohun ayé mọ́ àya. Bẹẹ kọ! Ọkàn rẹ̀ rọ mọ́ Kristi timọtimọ, Oun si gbẹkẹle Iyawo Rẹ̀. Oun kò ni nnkan kan ṣe pẹlu aṣa aye yii, to bẹẹ ti yoo fi maa kun etè, maa fi ina jó irun tabi maa wọ aṣọ ti kò bo itiju. Jẹ ki wọn pe e ni ẹni ti kò gbọ́ faarí tabi ẹni atijọ; ọkàn rẹ̀ saa ti pinnu pẹlu Rẹ̀.

### Panṣaga pẹlu Ayé

Jakọbu ri ọpọlọpọ ti wọn ti jẹ ki aye ja ifẹ wọn gba, o si kigbe: "Ẹnyin panṣaga ọkunrin, ati panṣaga obirin, ẹ kò mọ pe ibarẹ aiye iṣọta Ọlọrun ni? nitorina ẹnikẹni ti o ba fẹ lati jẹ́ ọrẹ aiye di ọtá Ọlọrun" (Jakọbu 4:4). Ijọ igbalode ti ode-oni ti ṣe panṣaga pẹlu ayé, ṣugbọn wọn ki i ṣe Iyawo Kristi.

O jẹ ohun ibanujẹ lati ṣe akiyesi pe ni akoko ogun nigba ti ọpọlọpọ ọmọkunrin fi aya wọn ti wọn fẹran silẹ lati lọ jà fun ilu wọn; lẹyin ti wọn si lọ tán, awọn ẹlomiran wá lati gba ifẹ awọn aya wọn, wọn si fi ẹni ti o lọ jagun silẹ lati maa ṣọfọ. Pupọ awọn eniyan ni wọn n ṣe bayi pẹlu Ọmọ Ọlọrun. Awọn ti wọn i ba jẹ́ olootọ si Kristi ti fún ayé layè lati gba ifẹ wọn. Wọn a maa lọ si ibi igbadun ayé gẹgẹ bi awọn eniyan ayé ti maa n ṣe. Wọn a maa lọ si ile ijo ni alẹ́, si ibi tẹtẹ ati si ibi nnkan ayé gbogbo. Awọn miiran ti jẹ ki wahala iṣẹ gba ọkan wọn kan, itọju ohun ayé si n pa wọn bi ọti, wọn si ti jẹ ki ifẹ Kristi jade kuro lọkan wọn patapata. Jesu mọ ọkàn ti Oun le fi ọkàn tán, O si n fi ọkàn tán Iyawo Rẹ̀.

**Ṣiṣe Aapọn**

Iyawo Kristi tayọ ki o jẹ wundia, ti a wẹ mọ́ ti a si wọ laṣọ ọ̀gbọ wiwẹ, ti o joko ti o si gbe ọwọ le ọwọ ni ọna ẹlẹgẹ lori timutimu ki o si maa reti bibọ Oluwa rẹ̀. Gẹgẹ bi awọn wundia ọlọgbọn, o gbọdọ ni ororo ninu kolobo rẹ̀ eyi ti i ṣe apẹẹrẹ Ẹmi Mimọ́. Nigba ti eniyan ba ri Ẹmi Mimọ gba, Ẹmi Ọlọrun maa n wọ inu ayé ẹni naa lati maa gbé ibẹ fun idi pataki ati maa tọ́ ẹni naa, ki O si maa fun un ni agbara ati igboya ninu iṣẹ Oluwa. Bayii ni Iyawo Kristi "si fi ọwọ rẹ̀ ṣiṣẹ tinutinu" (Owe 31:13). Oun jẹ alaapọn ninu iṣẹ ti Ọlọrun ti pe e si lati ṣe.

Ninu owe ti Talẹnti, Jesu ṣe apejuwe bi ijolootọ ati aapọn ninu iṣẹ-isin ti ṣe pataki to. Ọlọrun maa n fun wa ni anfaani fun iṣẹ-isin gẹgẹ bi agbara wa ti to. Lẹsẹkẹsẹ ti Baba Onifẹ ti n bẹ ni Ọrun ti pin awọn talẹnti ni ifẹ ti mu ki Iyawo Rẹ̀ bẹrẹ si i fi wọn ṣiṣẹ. "O fi oju silẹ wò iwà awọn ara ile rẹ̀, kò si jẹ onjẹ imẹlẹ" (Owe 31:27). Ni ibẹrẹ, boya o jọ wi pe iṣẹ rẹ̀ ko kọja ti awọn ara ile rẹ̀, ṣugbọn lai pẹ "o na ọwọ rẹ̀ si talaka" (Owe 31:20). O ri ẹbí ti o wà ninu aini "o fi ọwọ rẹ̀ le kẹkẹ́-owu," o bẹrẹ si i hun aṣọ fun awọn ọmọde, o n bọ́ awọn ẹni ti ebi n pa, o si n bẹ iya ti n ṣaisàn wò.

Bi awọn iṣẹ ifẹ ati iṣe-oore rẹ ti n di mimọ̀ bẹẹ ni afo tubọ n ṣi silẹ fun iṣẹ si i. Boya a pe e lati maa lọ bẹ ile itọju alaisan wò, tabi lati maa lọ sọ itàn igbala fun awọn ti o wa ninu tubu tabi fun awọn ti wọn kàn n rin kiri oju-ọ̀na ilu wa.

**Ibẹru Oluwa**

O n fiye gidigidi si orukọ rere ti Oluwa rẹ̀ ti ko i ti i de; awọn iṣẹ ododo ti o ni iyin wọnyii si n jẹyọ lati inu ọkàn rẹ̀ ti o kún fun ọwọ̀ ati ibẹru Ọlọrun. O jẹ ifẹ ọkàn rẹ̀ pe ki orukọ Rẹ̀ nla le ni iyin ninu ohunkohun ti oun n ṣe ninu ayé.

**Ororo**

"O dabi ọkọ̀ oniṣowo; o si mu onjẹ rẹ̀ lati ọ̀na jijin rére wá." Iyawo naa mọ̀ dajudaju pe ounjẹ futẹfutẹ ti ayé kò le ran oun, ṣugbọn ninu iyẹwu rẹ̀ o n bá Ọlọrun sọ̀rọ nibi ti o ti n gba agbára ati oore-ọfẹ fun iṣẹ rẹ̀ ti o pọ̀, o si n mu "onjẹ" rẹ̀ lati ọ̀na jijin réré wá. Igbesi-ayé adura ti o n gba jẹ ki ororo nì maa sun sinu kolobo rẹ̀ to bẹẹ ti "fitila rẹ̀ kò kú li oru".

**Aini Ororo**

Pataki pipa Ororo Ẹmi mọ́ ni a ṣe apejuwe rẹ̀ nipa fifi awọn wundia ọlọgbọn ati awọn alailọgbọn wé ara wọn. Awọn ọlọgbọn wọle pẹlu ayọ̀ si ibi ase igbeyawo, ṣugbọn awọn alailọgbọn n kọ́? iranṣẹ Ọlọrun kan nigba atijọ sọ nipa wọn bayii pe: "Dajudaju, òkunkun ainireti bo awọn ẹni ibanujẹ marun-un yii mọlẹ; wọn duro, wọn si ṣujọ si ẹnu ọna, nibi ti a ti tì wọn mọ́ ode pẹlu atupa wọn ti ina rẹ ti kú ti o si n fi dorodoro ni ọwọ wọn ti o n gbọ̀n. Agogo igbeyawo ti di iró agogo ọ̀fọ̀. Wọn ki i ṣe ọta ọkọ iyawo, wọn n ka ara wọn kún ọrẹ rẹ̀ ni. Wọn fi akoko falẹ titi lai ni ohun kan ṣoṣo ti o jẹ kò-ṣe e ma-ni; ijafara naa kò si ni atunṣẹ."

Ki ni ohun naa ti o mu iyatọ nla bayii wa laarin awọn ẹgbẹ meji yii? Gbogbo wọn ni wọn n reti ọkọ iyawo; gbogbo wọn ni wọn dide nigba ti igbe ta ti wọn si yi iná wọn soke lati pade rẹ̀. Nigba naa ni marun-un ri i pe awọn ti kuna lati ni ororo tó. Ororo jẹ apẹẹrẹ Ẹmi Ọlọrun. Wọn ti ṣe aibikita ni sisunmọ Ọlọrun timọtimọ ninu adura eyi ti i maa mu ki Ẹmi nì maa gbé inu ọkàn.

**Ainaani**

Awọn wundia alaigbọn jẹbi ainaani nipa ti ẹmi; nitori bẹẹ a tì wọn sode kuro nibi ase igbeyawo. Ijọ ti o wà ni Efesu ti fi ifẹ rẹ̀ iṣaaju silẹ, o si ni lati ronupiwada. Iṣẹ rẹ̀, laalaa rẹ̀ ati suuru rẹ̀ kò ni ere kankan niwọn igba ti ifẹ akọkọ nì ti kú. A gba talẹnti lọwọ ọkunrin ti o ni ẹyọ kan a si gbe e sọ sinu òkunkun biribiri lode nitori ti o kuna lati lo o. "Awa o ti ṣe là a, bi awa kò ba nani irú igbala nla bi eyi?" (Heberu 2:3).

**Iṣipaya**

Awọn ẹlomiran a maa ṣe ohun ti a ba ni ki wọn ṣe, ṣugbọn wọn ki i ri aini nla ti o wa yi wọn ká. "Ẹnyin ko ha nwipe, o ku oṣù mẹrin, ikore yio si de? wo o, mo wi fun nyin, Ẹ gbé oju nyin soke, ki ẹ si wo oko; nitoriti nwọn ti funfun fun ikore na" (Johannu 4:35). Iyawo Kristi ri i, ninu ogunlọgọ ọmọ-eniyan, bi ikore Ọlọrun ti pọ̀ tó ninu oko, ẹ̀ṣẹ ati ipọnju, aisàn ati ìṣẹ́, ijunisẹwọn ati adagbe; iwọnyi n pe e ni ija si iṣẹ. Iṣẹ rẹ̀ gbogbo jẹ́ ti aanu, iṣẹ rẹ̀ si jẹ iṣẹ ifẹ ati "li ahọn rẹ̀ li ofin iṣeun."

**Ere**

"Awọn ọmọ rẹ̀ dide, nwọn si pè e li alabukúnfun, ati bãle rẹ̀ pẹlu, on si fi iyin fun u." Ere ologo naa yoo ti to nigba ti Ọba yoo wi fun un pe: "Ẹ wá, ẹnyin alabukun-fun Baba mi, ẹ jogún ijọba, ti a ti pèse

silẹ fun nyin lati ọjọ ìwa" (Matteu 25:34). Ni iṣẹju naa gbogbo idanwo ayé ti o ṣú dùdu ti o si kún fun laalaa yii yoo parẹ kuro loju rẹ̀, idahun rẹ̀ yoo si jẹ "Oluwa, nigbawo ni awa ri ti ebi npa ọ, ti awa fun ọ li onjẹ? tabi ti ongbẹ, ngbẹ, ọ ti awa fun ọ li ohun mimu?" Oun yoo si dahun pe: "Niwọnbi ẹnyin ti ṣe e fun ọkan ninu awọn arakunrin mi wọnyi ti o kere julọ, ẹnyin ti ṣe e fun mi."

**AWỌN IBEERE**

1 Awọn wo ni yoo jẹ́ Iyawo Kristi?

2 Darukọ diẹ ninu awọn iwa rere Iyawo naa.

3 Ki ni pataki jijẹ wundia nipa ti ẹmi?

4 Ki ni mu iyatọ wá laaarin awọn wundia ọlọgbọ́n ati awọn alaigbọ́n?

5 Apẹẹrẹ ki ni ororo jẹ́ ninu Iwe Mimọ́?

6 Ki ni ẹkọ pataki ti a ri di mú ninu owe awọn wundia?

7 Ki ni talẹnti?

8 Ki ni a wò ki a tó pin talẹnti?

9 Ki ni oluwa naa n reti lọwọ awọn iranṣẹ rẹ̀ ni igbà bibọ rẹ̀?